**WANTED**
Agents from all important towns in the West to distribute
**IROHIN ONIGBAGBO**
Write to
Circulation Manager
9 Western Avenue,
Surulere-Yaba.

**Irohin ONIGBAGBO**

**J. A. Fagbohun**
Organ, Harmonium Repairer.
Sales & Service
153 Agege Motor Rd. Atewolara
Mushin.

NO. 92 NOVEMBER 3—9 1963 KOBO META

# ISOJIEKO Kamama

## Onisoji Dokita Dahunsi Sebebe

"... Nigeria, papa ilu Eko se alaini ... ere. E wo bi ese ti mu iyapa wa. E wo iwa ilara ti o wa larin ile wa. E wo o bi ife ti nsaki larin ara wa. Gbo gbo enia si wa labe agbara ese.

Awon enia pa ogo Olorun ti ki dibaje da si aworan ere enia ti idibaje, nwon yi otito Olorun pada si oke elesin Kristi toto gbodo tako awon iwa ibaje ti nfarahan larin awon Ijoba ati awon enia laifoya. Ti a ba ku na a o jebi nla. "

Awon oro wonyi jade lenu onisoji Dokita Dahunsi nibi Isin Isoji ti o o sese pari L' Eko.

Isoji na kamama, o bu aya. Koni gbagbe si ni pelu Ogunlogo awon olufokansin, l'okurin l'obirin, omode ati agba lati oniruru ile Olorun lo pejo si bi ipade na ti a se ni ilu Eko l'ose to koja. Ko si Anglican, Metodisi, Baptisi, Afrikan, Kerubu ati Serafu ati be lo' sugbon gbogbo awon olufokansin pejo gege bi agba jo kan n inu Kristi.



ALUFA IDOWU
ti Yaba Methodisi

Ipade Isoji na bere ni ojo aje l'ose to koja, o si pari ni ojo aiku ose yi. Gbogbo nkan lo leto leto nibi ipade na labe akoso alaga ti a yan fun ojo kokan. Lara awon alaga na ni a ti ri Olori Ijo Metodisi ile Nijiria, Dokita J. O. E. Soremekun Alufa agba F. O. Segun, Apostoli S. G. Adegboyega, Olori Ijo U. N. A. Eni owo J. F. Ogunko, Olori ijo Church of the Lord Eni owo Ositelu.

Alaga igbimo isoji gbogbo ijo yi, Eni owo Aboyade Cole wa ni gbogbo ipade na.



BISHOP ODUTOLA
Asoju Agba ijo CMS

## Okotie Eboh: Popu Gba Lalejo.

NI ojo kokandinlogun osu kewa odun yi ni Popu Paul kefa gba oloye Festus Okotie Eboh Minista alabojuto eto owo ti ijoba apapo Naijiria lalejo ni ibugbe Popu ni Vatican City ni ilu Rome.

Oloye Festus Okotie Eboh ndari lati ile Germani nibi ti o ti lo ba won se ipade apapo ti ile ifowopamo ti agbaiye laipe yi.

Popu mimo na si gbadura fun Oloye Okotie Eboh ki o to fi aye ile Popu sile lati ma lo si Londonu fun ipada wa si Nijiria.

## Ojo Agan fun Egbe Akorin Ijo Salem

AWON egbe akorin ti ijo Salem African Church se ajodun won ni ojo isimi ti ise ojokerindinlogbon osu to koja. Isin na larinrin pupo, awon akorin na si fi asayan orin aladun da opolopo awon enia ti o pejo sibe laraya. Ajodun yi ni iketadinlogbon ti egbe akorin ijo na.

Ninu oro iyanju re si awon omo egbe yi, Alufa Oluwole Ajediti so pe orin kiko je ona kan ti enia ngba tan imole ihinrere Kristi. O kesi gbogbo awon akorin na lati fi emi won fun Kristi ati lati jeje pe awon yio ma fi ohun won ati ohun elo orin yin.

Ni isin ale ojo na, Alufa Abom ki awon ijo na fun orire ti won ni nipa egbe akorin rere won

Lati fi kadi gbogbo ajodun yi, egbe akorin na ko awon orin oloyinmomo kan ti a pe akole re ni "Jerusalem titun" (The New Jerusalem.)

Ile Olorun Salem ti ise ibujoko Arsidikini ijo African le fowosoya pe on ni egbe akorin ti ko se fowo ro sehin larin gbogbo ijo Eko.

E o ranti pe ni enu ijometa yi ni Ijo Salem se ajodun ikore won ti gbogbo awon olujosin nibe atonile ati alejo si nki egbe akorin na fun ohun orin ibile titun ti won gbe jade.

## Patterson Pada

NI aipe yi ni olori Diosi. iwo Orun Afrika Arsibisobu Patterson pada si iliorun Naijiria lehin isinmi die.

Ninu oro re Enugu o ni isin yi fun on ni anfnil ati jiro ro pelu Olori Ijo Katoliki ni ilu Vatican.

FUN OHUN OSO ILE YOWU TI A FI IGI GBE TI O SI BA OJU MU LO SI ODO
**SHOYEMI & SONS FURNITURE SERVICE,**
26 Adewusi Street,
Ikorodu Road
Yaba, Lagos.

**Ni ohunkohun ti o ba je mogun tabi egbogi, ma darabduro lati ri**
ALDER PHARMACY
CHEMIST AND DRUGGIST
69, Old Yaba Road,
Ebute Metta.

Ema ka iwe "Irohin
**PEOPLE'S MONITOR**
dede E ma polowo oja yin ninu re

## ORO OLOTU:- EMI NFE.

OPOLOPO awon leta ati ibere ni o ti nro wo iie itewe yi ti nwon nbere fun opo iwe yi si i, ati lati ni awon eka kakiri awon orile-ede Ghana, Saro (Sierra Leone) ati Liberia.

Ife inu awon olutewe yi ni latı ma fi iwe onigbagbo ti o lagbara yi fun awon orile-ede miran ti nso ede Gesi ni ile Afrika yato si iie Nigeria nikan.

Sugbon inawo nla ti o ga nipa tite iwe na ati gbigba awon osise ti o yekoro si ile itewe na ni awon isoro die ti iwe na Koju si ni akoko yi.

Awon eri ti o daju ti wa nisisiyi pe gbogbo awon onigbagbo ni gbogbo ile alailoba yi ti nfe iwe na Kakiri.

Gbogbo awon onigbagbo ni ise wa fun lati se lati le jeki iwe yi fun awon enia ile Afrika ni ile itewe onigbagbo ti o lagbara.

Eyi je iwa laye ihinrere, nitorina a nfe iran lowo ki iranlowo ti enikokan ba le fi ranse lati fi ran ile itewe yi lowo. Iru awon iranlowo wonyi le je owo, awon iwe fun ile ikawe ile itewe na tabi lati wa fun amoran ojukoju.

Gbogbo wa ni a ni ise lati se ninu ogba Oluwa.

# Awon oniwasu oni



Eyi ni aworan awon Anglican Alufa ti o pe jibi ipade kan laipe yi

### Anglican Churches

ST. DAVID'S
7. 30 A.M. Holy Communion
9. 00. A.M. Mattins
6. 30 P.M. Even-Song

ALL SAINTS YABA
8. A.M. yoruba Mattins
9. 15 A.M. English Mattins
6. 30 p.m. Even-Song

ST. JAMES IDI-ORO
Morning Cat S. O. Layode

A. M. C.Odi-Olowo Morning Cta G. B. A. Ransford

U. E. A. C.
MUSHIN Morning Bro. J. O. Oluwatayo

HOLY TRINITY
9. a.m. Dr. K. Sagoe
6. 30 p.m. Mr. J. O. Jones

SURU-LERE
9. a.m. Mattins Rev A. O. Taiwo

HOLY TRINITY IKATE
9. 30 a.m Rev. A. O. Ayodele

### The Ghurches of the Lord

ELE GBATA
Morning Prophet J. A. Fabusoro
Evening Leader S. B. Olugbode

SHOMOLU
10 a.m. Mr. Olusanya
6. 00 p.m. Mr Olusanya

### Anglican Church

CATHEDRAL LAGOS
9. 00 a.m. The Provost
6. 30 p.m. Rev. R. V. Earnshaw-Smith.

IKORODU
10.00 A.M. Bro. A. I. Pelu
7.00 P.M. Sis. S. Ogunfile.

IGBOGBO
10.00 A.M. Bro. V. K. Bamgbala.
4.30 P.M. Bro. C. A. Oluwadaini.

GBERIGBE
10.00 A.M. Bro. E. Orenuga.
4.30 P.M. Bro. A. Aina.

AGURA
10.00 A.M. Bro. Ademola
4.30 P.M. Bro. Ogundeji

OKE-ELETU
10.00 A.M. Bro. J. Olatunji
4.30 P.M. Do

BAIYEKU
10.00 A.M. Bro. C. A. Oluwadaini.
4.30 P.M. Do

EWU—ELEPE
10.00 A.M. Bro. W. Dehinsilu.
4.30 P.M. Do

EREFUN
10.00 A.M Bro Akinbiowu
4.30 P.M. Do

WILLIAMS MEMORIAL
8.30 A.M. English
10.00 A.M. Yoruba
7.00 P.M. English

MUSHIN
10.00 A.M. Yoruba
5.00 P.M. Yoruba

APAPA ELEMU
10 00 A.M. Bilingual
5.00 P.M. Bilingual

APAPA AJEROMI
10.00 A.M. Bilingual
5.00 P.M. Bilingual

BORNU CRESCENT
10.00 A.M. English

KIRIKIRI PRISON
2.00 P.M English

KIRIKIRI VILLAGE
10.00 A.M. Bilingual

OSHODI
10.00 am Yoruba Bro. S A Ogundeyi 6 30 pm Yoruba Bro. 1 O Fagbola

ABULE-IJESHA
10 00 am Yoruba Mr. S.O. Olajubu 7.00 pm Yoruba Mr. S E S Dawodu

IMEGBON
10. 00 am Yorubr Bro J O Adegoriolu 7.00 pm Yoruba Bro. E A Adekanmbi

SOMOLU
9 00 am Ibo Bro G O Ekpo

IJU
10 30 am Yoruba Mr. A Banjoko 4 30 pm Bro C A Akindehin

ABULE-OJA
10. 00 am Yoruba Bro S. A Fasanu

OBASA JRN GIRLS REMIND HOME
9 30 am Yoruba Bro J O. OJo

BOYS REMAND HOME
9.00 am Yoruba Bro J.O laniyan

TINUBU
8 30 am Yoruba Bro W Osin 10 00 am English Rev W J Wood 7 00 pm English Bro S E Creppy

TINUBU
8 30 am Kroo Bro A Potey
5 00 pm ,, Bro D K Peter
5 00 pm ,, Bro E O Daniel

### Merhodist Churches

Olowogbowo
100 SA.M. Yoruba Revd A.. 0. Solarin
.0 .P.M. English Rev. A. S. Solarin

OBUN-EKO
1000 A.M. Yoruba Bro. A. Olaniyan
00.P.M. Yoruba Rev. S. A. Akinbo

FANTI
5.00.P.M. Fanti Bro. N. N. Onwuka

IKOYI
10.00.A.M. Yoruba Bro. M. O. Dada
7.00.P.M. English Rev. M. B. Olaniyan

IBESE
10.30.A.M. Yoruba Bro. A. Daodu
5.00.P.M. Yoruba Bro. A. Daodu

IPETU
10.30,A.M. Yoruba Bro. Taiwo
5.00.P.M. Yoruba Bro. H O. Adebayo

OKO-OMI
10.30.A.M. Yoruba Bro. E. A. Fasogbon
5.00.P.M. Yoruba Bro. S. O. Ajayi

OTEA
10.00.A.M. Yoruba Bro. L. A. Adedeji
4.00.P.M. Yoruba Bro. L. A. Adedeji

YABA
8.30.A.M. English Rev. E. A. O. Idowu
10.00.A.M. Yoruba Bro. O. Fayemi
5.30.P.M. Yoruba Sis. P. M. Akinbo
7.00.P.M. English Sis. J. Obi

## IRONBAR DI BISHOP TITUN

Ni ojo fri'day ose ti o koja ni awon ijo African church ya Archdeacon O.N'Ironbar si mimo bi bishop titun fun agbegbe calabar ni ijo African Bethel Cathedral Church ni eko'

Ni ojo kanna ni awon alufa meta bo si ipo Archdeacon

ADVERTISE

IN THE

Peoples Monitor

It's getting brighter every week

# FA ARA RE SUNMO OLORUN

L ati owo Alufa Gleaner

**NINU oro ikehin re si Jobu, Elifasi ti ise okan ninu awon ore meta ti o ni gba a niyanju pe ki o fa aira re sunmo Olorun ki alafia ati irora bale je tire. Imoran yi toka si ona oye ti o gajulo ati ohun ti o sanfani julo.**

Oro Elifasi na lo bayi: "Fa ara re sunmo Olorun iwo o si ri alafia nipa eyini rere yio wa ba o". Jobu 22:21.

Ogunlogo awon enia ni o gba esin Kristi lai fi tokantokan fa ara won sunmo Olorun nwon ko mo o rara. Sugbon esin tooto duro lori ero pipe nipa Olorun nipa iwa ti ise re ati nipa ola re.

Fifa ara eni sunmo Olorun je mo ero toto nipa re ati irepo pelu re. Bakanna si ni o je okanna pelu igbagbo ninu ati isokan peln re.

Oro yi, "faramo" funrare lagbara pupo. Ale tumo re si "Jowo ara fun Olorun "sunmo Olorun tabi dapo: mo Olorun."

Ki a to le faramo Olorun a koko ni lati faramo gbogbo isipaya ti Olorun gbe siwaju wa nipa ara re ati ife Re. Ona meji pere ni a le gba lati ni oye nipa Olorun. Ekini le je nipa akiyesi lasan sugbon ekeji ni nipa siso ohun ti o nfe, ko si eyiti ko ni iye lori sugbon sise ife Re nikan ni ona ti o ye koro ti o si dara lati gba mo O.

Gbogbo eda gbodo ma lepa ona lati fa ara won sunmo Olorun ninu gbogbo igbokegbodo won. Nipa kiko oro re, adura ati ifaramo ile Olorun ati ni ona miran nwon le fa ara won sunmo Olorun.

Siwaju si i, ejeki a ro iyorisi fifa ara eni sunmo Olorun. Elifasi ni " Iwo o si ri alafia" ko tun si alafia ati ayo kikun ti o tayo fifa ara eni sunmo Olorun Alafia Olorun nikan ni o ta gbogbo oye enia yo. Aiye ko le fi iru alafia bayi fun ni.

Elifasi si tun soro lori iyorisi miran. "Nipa eyini rere yio wa ba O.

Laiseaniani, Elifasi nro nipa ibukun si aiye yi beni awon ibukun na si po jojo.

Sugbon ara, rora foju emi wo ibukun pataki ti ise ogun elesin Kristi. A w o gbogbo ese mu, okan soji, ide wa di ominira, itegun esu fo, gbogbo ailera ka kuro, igbesi aiye di ibukun fuu awon elomlran, a segun oro iku, okan ri alafia, igbala si daju ni aiye ainipekun. A w o n ibukun wonyi je ohun ayo nla ati anfani ti o tobi julo ti o le je ti awa eda.

O wa ku sowo olukaluku lati fa ara re sunmo Olorun ki alafia ti o tayo si oye enia gbogbo ba le je tire. Nje iwo mura tan lati se eyi? Olorun wa nitosi, o si ti se-tan lati fi ibukun yi fun O Ma jeki o koja re. "Fa ara re sunmo Olorun ki alafia ati irora ba le je tire."

### ADURA

Ojo isimi Ogun lehin Metalokan.

Olodumare ati Olorun a l a n u julo, awa mbebe lodo re, ninu opolopo ore re pa wa mo kuro uinu ohun gbogbo ti yio panilara, ki a le mura tan li ara, ati li okan, lati ma fi inudidun se ohun wonni ti o fe ki a se, n i p a s e Jesu Kristi Oluwa wa Amin



## ORIN WA ONI

"Emi o yin Eleda mi" je orin karun le logbon ninu iwe orin Metodisi. Ni igba kan ni ilu kan ni ile Yoruba okunrin kan ti o nse inunibini si awon elesin Kristi saisan de oju iku. Awon ara ile re ti so okan nu. Sugbon ni ojo kan Alufa Oyinbo kan wole to okunrin yi lati gbadura fun. Lehin adura, ara okunrin yi mokun, o si so lokan ara re pe Olorun ni o wo on san.

Bayi ni o di onigbagbo, orin yi si je okan ninu eyiti a ko lojo ti o lo si ile Olorun ni igbesi aiye re, o nwasu ihinrere o si ma nko orin yi nibi iwasu re.

Ogbeni Isaac Watts eniti a bi ni 1674 ni o ko orin na. Psalmu kerindiladojo ti o je okan ninu awon akopari Psalmu marun ti a npe ni Haleluya ni o fun Watts ni isiri lati ko orin na sile. A npe awon Psalmu na ni Haleluya nitori nwon bere pelu e yin Oluwa, nwon si pari pelu oro kanna.

isa ac Watts je ojogbon ninu orin kiko. O wo bi gbogbo nkan ti nlo ni aiye o wo titobi Olorun ati ise iyanu re lara awon omo enia, o si ri i daju pe Iyin lo ye fun Olorun.

O ku ni 1748, a si ma psaba ko orin re si ohun Dresden, ti J. Schmidlin ko ni 1770.

1. Emi o yin Eleda mi
   Nisiyi, ati lehin 'ku
   Emi o f'agbara mi yin;
   Ojo iyin ki o koja;
   Nigbat' iye on ero wa
   Titi igba ainipekun.
2. 'Bukun f'eni t'o gbekele
   Olorun Israel' t'o da
   Orun, aiye, atekun won;
   Otito Re duro sinsin.
   Ongb'akuse, O mbalaini
   Ileri Re ki se asan.
3. Jesu nf'iriran f'afoju;
   O ngb'emi alare soke;
   O nf'alafia f'okan ebi;
   O nran alejo li owo,
   Opo, at'alaini-baba,
   O nda ara-tubu n'ide.
4. Em'o yin 'gba mo wa laye;
   Nigbat'iku ba gb'ohun mi
   Iyin y'o gba okan mi kan;
   Ojo iyin ki o koja,
   Nigbati ye on ero wa
   Titi igba ainipekun.

## IDAHUN IBERE

### Arakunrin kan kowe bere pe, a o se fi rere segun ibi.

Ninu Episteli P a u l s awon ara Romu ori kejila ese kokandilogun de iketalogun Paul se alaye pe o je iwa eda lati fi ibi san ibi ati lati fi ore san ore. Sugbon o so siwaju pe elesin Kristi gbodo tayo eyi ko gbodo g b e s a n fun rare, ko si gbodo huwa bi enipe o nreti idajo Olorun. Nitorina ko ye fun u lati se ohunkohun, kanran be bi ti mo ife ati anu Olorun, o nilati fi awon ofa wa siile fun u. Ise re ni lati fi ife fa awon ota ki o si mu arankan kuro. Nipa be o nko ina jo sori ofa. Ama nsegun ibanuje nipa s i s u n mo Olorun. Boua ni ama nsegun enia ibi nigbati a ba fa won pelu ife atokan wa. Ibi nyipada nipa inurere ninu isesi oro ati iwa wa. Awon nkan wonyi soro, sugbon nipa ore ofe Olorun a le se won.

## ORO IYANJU ONI

Iponju je ohun ti ale fi nwon enia. Gege bi o ti ye lati fun ewe pa ki o to le mu o orun didun re jade, bakanna ni a gbodo dan eda miran wo ninu ina e leru nla ki won to le mu talenti rere ti nbe ninu won jade. Gege bi oro Jobu nigbati a ba dan-mi wo ninu ina eleru, ngo o yo jade gege bi wura.

# Iranwo Owo Jaburata Lati ILE Geesi

ADEHUN ti ile Naijiria se pelu ile esei laipe yi mbu gogbo owo ti ile Geesi fi ran ile wa lowo lehin ti a gba ominira le ni poun meji le logbon milionu. Eyi jade ninu irohin pataki ti ijoba ile Geesi gbe jade lori iranwo ti won nse fun idagba-soke orile ede miran

Irohin na t o k a si pe gbogbo iranwo yi bere pelu adehun kan ti ile mejeji jo se lati ri pe ile Naijiria ngba owo ti o to eyiti o nri gba nigbati o wa labe ile won, pelu awon owo ti o to poun mejila milionu fun eto ilosiwaju ise aje odun marun ti o bere ni odun 1956.

si 1963 gbogbo inawo yi nigbati a siro re je milionu mejidinladojo. Larin odun 1963 si odun 1964 a fiyeni pe owo yi yio to ogosan si igba milionu poun.

Iranwo owo miiran ti Ijoba ile Geesi nfi sowo si awon ile miran ninu egbe Common-wealth je odunrun milionu poun. O to adojo milionu ti won ngbe sile ni ododun fun awon idagba soke awon ile larin egbe Commonwealth.

## Milionu marun fun ile eko Bello

Lodun to koja, Ijoba ile Geesi fi poun marun milionu ta ile Naijiria lore fun ilosiwaju awon ile eko giga. Ninu owo yi, poun meji milionu yio lo fun ile eko Ahmadu Bello, a o si da iyoku duro fun awon ile eko oluko ati ile eko ti ise owo.



Ogbeni D, C. Aniakor on ni yio fi irohin ranse siwe yi nipa odun Keresimesi lati Ilu Oyinbo lodun yi.

## Milionu mewa fun Idagbasoke

Ile Geesi si tun ya ile Naijiria ni poun mewa milionu fun eto idagba-soke odun marun (1963–68). Owo yi wa fun ohunko-hun ti ile Naijiria ba fe gba lati ile Geesi ni odun meji ti o ba bere eto na. ile na ti tun fi poun kan abo milionu sile fun rira irin oko reluwe. Yato si gbogbo anawosi yi, ile Geesi ti jeje lati lowo ninu owo ti a o fi se ona omi odo oya (Niger Dam).

### Inawo

Okan ninu awon eto ti o tobi ju ninu inawo bi milionu egbegbaarun poun fun awon ile okere, ni anawosi re fun ilosiwaju orile ede. Ni odun 1962

## OKOTIE EBOH Dupe Lowo ile. Ifowo pamo Agbaiye.

### Okotie-Eboh dupe lowo ile Ifowo Pamo agbaiye.

Olotu eto inawo Ijoba apapo ile Naijiria Oloye Festus Okotie-Eboh ti dupe lowo ile ifowopamo agbaiye (World Bank) ati Owo esu agbaiye (International Monetary Fund) l'oruko ile Naijiria fun gbogbo iran-lowo won.

Oro ope na jade lenu oloye Okotie Eboh ni ibi ipade ti awon igbimo olu-dari ile ifowopamo mejeji ti ise eka agbajo orile ede (United nations)

Awon mokandinlogun ti o wa ninu igbimo na ni won ma nba ise ile ifowo-pamo na lo ni gbogbo asiko

Oloye Okotie Eboh so ninu oro re pe awon orile ede ti ndagbasoke le ma gboju won soke si awon ile owo ti agbajo Orile ede pelu igbekele to o daju fun iranwo tooto.

Siwaju si, Oloye Okotie-Eboh ni ile Naijiria ro pe o to osi ye ki a ma lo awon owo ti o wa bi isura ninu ile owo na fun iranwo pataki ni ile ti nsese nda-gbasoke. O daba pe ki ile owo na fikun owo ti nya awon orile ede, Ki o si tun tari isura owo die si egbe idagbasoke agbaiye (Inter-national Development Ass-ocation) ti ise eka re, ti o si gba ki awou orile ede ma fi owo ile won san gbe-se ti won je.

Oloye Okotie Eboh bere fun ifopinsi gbogbo ilosoke ati ilosile owo, ati pe ki a wa oye owo ti odaju ti ko si ni ye fun ise aje.

Ni ipari oro re o kan sa-ra si awon igbimo na ti won yan omo ile Afrika gege bi omo egbe igbimo. O ni eleyi yio fun awon ile enia dudu ni anfani lati soro pelu ohun kan.

Onirohin wa kan fiye ni pe, Orile ede Senegal ni a yan lati ile enia dudu omo egbe igbimo.

## Amerika Faramo eto koko

Ile Amerika ti faramo eto titun ti awon orile ede fe gbe jade lati le fi opin si ailo dede owo ori lod-odun.

Sugbon asoju ijoba ile na Ogbeni Henry Brodie se ikilo kan fun ipade agb-ajo orile ede (United Nations) ti nbojuto koko lai pe yi pe ki awon ma gbe owo ti o ga ju le ori koko.

Gege bi oro re' sise bayi yio le awon ti nra koko sehin yio jeki won wa owo miran' yio si di eru wuwo le awon onisowo.

Siwaju si' Ogbeni Brodie se alaye pe ohun ti aiye nfe ni owo niwonba ti fa awon enia ti ngba koko mora' ti yio si tun mu ilosiwaju ba owo na.



Alufa Howard Jones

Kere o

A nfe awon

Agenti

Lati ma ta iwe

IROHIN OINGBAGBO

ATI

PEOPLES' MONITOR

kakiri ile Karo O ojire Koni wahala ninu. Jere elokan losose nipa tita iwe yi Kowe si oga ile ise:-

9. Western Ave. Suru-lere
P. M. Bag 1057 Yaba Lagos

# OTITO INU

## IJO METODISI IKATE PEGEDE

Nigbakugba ni a ma nfi ye mi pe, o ma ngba asiko die ki a to le gbe egbe akorin ti o sun won dide, sugbon ile Olorun' Metodisi ti Folawiyo bankole ni Ikate fihan gbangba pe eleyi ko ri be.

O je iyalenu pe iru odo egbe akorin ti ijo a le se ohun ribiribi ni asiko kukuru ti ati da sile Iru ayeye ti egbe na se ni ojo isimi to koja ini-ibi isin ikore ile Olorun won ko re fenuso. Odara rekoja aala. Eni yowu to je adari egbe akorin ti oje odo sugbon ti o gbese yi gba iyin pupo.

Ise re mu eso rere jade O seun, Ijo Ikate.

## KO FUYI RARA

IJO U. N. A. se ajo nla won laipe yi, osu kan lehin ti Ijo African se ti won. Oniruru eto ni a si ni gbangba lara won si n awon isin.

Ni ile Olorun Chris- Church ati Jehovah Shall om, orin kiko ko gbesese ko si fanimora. A ko tile gb o orin ibile rara. Gbogbo eto ipade ojo na ko ye ge an o. Awon Bisobu meji lo tile pe fun Isin ti Christ Church.

Ijo U. N. A. dagba ju ijo African lo, sibe ijo odo yi se bebe ju awon ti o je agba.

Ogoro nkan ni ko lo deede ninu ile Olorun wa, lara won ni a le toka si aile-to, ati ailoye to. Eleyi ko ye ko ri be pelu ile Olorun U. N. A. nitoripe alakoso agba Ijo na Eni Owo Ogunko ni eko ati oye ti o ye koro, 'Eto ni pe ki eto igbimo ti odun ti mbo be su o die.

## ISE IYANU

Lati igbati a ti te irohin ise iwosan woli Kogbe-regbe jade ni a'ti ngbo orisirisi ibere. Opolopo ni iyemeji si ododo iwosan na yio soro fun awon alai-gbagbo bi Tomasi lati gba nitoripe lehin iku Aposteli Joseph Babalola ile Naijiria ko ti ri iru nkan be.

Wo oju ewe keje

## ILE OLORUN ALL SAINTS' S'AJODUN KOKANLELOGBON

NI ojo isimi ti ise ojo ketadinlogbon osu kewa odun yi ni awon ijo ile Olorun ti All Saints' Church, Yaba bere ajodun Kokanlelogbon pelu isin alarinrin kan ninu ile Olorun na.

Ni ojo Aje ti ise ojo ke-jidinlogbon ni awon ijo ile Olorun na si tun fi awo-ran ti igbesi aiye ti Jesu Kristi han ninu ero alawo-ran (Cinema) ti nwon se ni agbala ile Olorun won ni deede agogo meje irole.

Ki nwon to bere, ala-bojuto ile Olorun na, Alufa C. A. Akinbola gba adura lehinna o so fun awon ijo na pe olukuluku ni lati mo daju pe awa enia elese ni Jesu se ku.

Ni ojo kokandinlogbon osu, awon ijo ile Olorun na se ijiyan lori pe 'Awon Obinrin je onigbagbo ju awon Okunrin lo" Iya afin B. A. Sangowanwa ati Ogbeni S. P. C. Ude-zue lo si je Oludaba. Ogbeni L. T. M. Awokoya B. Sc (London) ati iya afin T. C. Taylor lo si je ala-tako. Ogbeni, Adajo agba J. A. Adefarasin, Iya afin Remi Aiyedun, Ogbeni Osita Aduba ati Iya afin Yejide Rogers lo si se ayewo jiyan na.

Lehin na ni ale ojo yi ni awon odo ijo na tun se ere kan ni gbogan ile eko ti Methodist Boys' High School, Broad Street, L'Eko. Ere na ti a pe akole re ni "Ipinnu ti a kabamo" dun gan, Gbogbo awon enia si gbadun re.

Ni ogbon ojo osu, ida-raya bolu ifese gba ni agbala ile Olorun won. Awon Odo omobinrin ati awon agbalagba okunrin ti o ti darugbo ni won figa gbagba.

Ni ojo kokanlelogun osu kewa odun yi awon ijo na si se isin kan fun awon omode.

Ni ojo ekeni osu yi ni awon ijo ile Olorun na se isin iranti ti awon enia mimo ti ile Olorun na njoruko mo.

Ni agogo mefa owuro. Isin Onje Ale Oluwa ni-kan ni, orisirisi alufa lo si p'ejo sibe.

Ni ale ojo na Eni owo S. O. Odutola se isin igbowolelori (Confirmation) fun awon omo ijo. Ninu iwasu re, o kan sara si awon Ijo All Saints' fun akitiyan won, o si ro won lati ma te atesiwaju ninu ise rere gbogbo.

Ni ojo keji osu ni awon ijo wa se apejo fun faaji labe alaga Ogbeni J. O. Nye ni Agbala ile Olorun won.

Lati fi kadi gbogbo ajodun yi, ao se isin ope kan ni ojo isimi ti ise ojo keta osu yi ni agogo mesan.



Aworan yi nfi apakan awo Ogunlogo enia han nibiti nwon pejo si ile Olorun kan ni Eko nii ojo isimi to koja ki won to towo lo si oban Tafawa Balewa fun isin pupe isoji.

## Igboran San Ju Ebo Lo

LATI OJU IWE KE

un yi ni iya yi ba ko ejan o ba ro fun Baba onisegun ohun ti oju re ri Baba onisegun si fi esi fun bayi wipe se o ye, e omobinrin na ni o ye on. Baba onisegun ni ti o ba ti ye e nje ma lo sile re, iya na si yi pada lesekan na o doriko ile re.

Nigbati o di odun keji iya yi tun mura o dori ko ile olowo, nigbati o si ku die ki o de ile olowo ariwo ija nla ni o tun gbo ti o ti sele bi olowo na se kigbe bayi wipe a se Aja ni iwo omobinrin yi ca o mo pe Aja ni e on ki ba ti fe e ti o ba je pe on mo pe Aja ni iwo Omo-binrin dada yi.

Nigbati iya yi gbo bayi biri ni o yi pada ti o si dori ko ile Baba onisegun o tun ko o ro fun Baba onisegun on ti oju re ati ti eti re gbo ti o ri ni ile olowo yi Baba onisegun si tun so fun pe se o ye, iya na si da Baba onisegun lohun pe o ye on.

## IYAWO OBA

Laipe ojo iya yi tun mura o dori ko ile oba lati lo wo omobinrin re eketa sugbon bi o ti ku die ki o de ile oba ni awon omode ti o nsere ni ita oba ni won ri iya yi ti o nbo lokankan, lesekese ni won ti sare wo inu ile oba lo ti won si lo so fun iyawo oba pe iya re mbo wa ki, were ni iyawo oba yi ti so fun oba oko re ti won si gunwa sori ite laisi ija tabi ariwo, ni iya omo arewa iyawo oba ba ki awon mejeji won si se ni alejo, inu iya na si dun pupo nigbati o setan ti o fe ma lo won se ni alejo dada on na si dupe lowo won pupo. Ni were ti o kuro nibe o dori ko ile Baba onisegun.

Nigbati o de odo Baba o bu si erin, Baba onisegun wa bi iya yi ohun ti o ri ki o to ma rerin. Iya yi

WO OJU EWE KEJE



Agbajo owo ni a f i so aiya, toto o se bi owe. Bakanna n i awon alufa *t i* e nwo aworan won iparapo lati karamasiki mo eto isoji ti a se laipe yi.

# IsoJi Eko Se Ipinnu

## LATI OJU EWE KINI

### ISIN IDUPE

NI ipari isoji na, a se isin idupe kan ni odan Tafawa Balewa l'Eko ni ojo isimi ketadinlogbon. Alufa agba F. O. Segun ni o se isin na dipo Adele Olori Bisopu iwo orun Naijiria Eni owo S. O. Odutola ti ko le wa nitori isinku Alufa Alafade ni Ibadan.

Ninu oro iyanju re Alufa Agba Segun dupe lowo Olorun ti o fi ogbon hna Ologbe Howells lati da igbimo isoji ti gbogbo ijo Kristi sile. O dupe lowo onisoji Dokita Dahunsi fun aayan re, o si gbadara pe ki Olorun jeki awon enia mo asiko isoji yi soto fun rere.

### IPINNU NLA

NI kete ti Alufa na pari oro re ni Akowe Igbimo isoji, Ogbeni E. O. Daniel so nipa ipinnu kan lati fi tako iwa ika, ailanu ti iwa alaiwabi Olorun he awon alawo funfun enia si awon alawodudu Amerika.

Eniti o gbe ipinnu na dide ni Major Barika ti egbe omo ogun Igbala (Salvation Army). Alufa E. H. Williams ti ile Olorun Union Baptist lo gbe e lese. Ninu ipinnu na ti gbogbo awon omo egbe igbimo isoji fowosi, ti awon ti o pejo si gba, nwon ni o tilejepe a ti ngbo irohin iwa ika, ailanu ati iwa alaiwabi Olorun ti awon alawo funfun kan nhu si awon enia dudu elegbe wa, ati bi o tileje pe ijoba apapo ile Amerika ati Olotu ile na, Are Kennedy ti tako iwa yi, ati pe bi o tileje pe iru iwa yi je atako si emi elesin Kristi tooto, ati bi o tile je pe a faramo ona ti ijoba ile Amerika ti gba lati dawo iwa ibi yi duro,

Nisisiyi awa egbegberun ona egberun enia ti ise asoju awon ile Olorun Protestant ni Naijiria ni bi kade wa ojo oni ti ise ojo ketadilogun osu k e s a n odun yi n i odan opopo Tafawa Balewa labe akoso igbimo isoji gba pe

1 Ki a fi iwe ifaramo wa ranse Are ile Amerika Ololа Kenedy lati o w o Ijoba ile Niajiria fun gbogbo ona ti Ololа Kenedy ngba lati tako iwa ibaje alawo funfun ni ile Amerika se atilehin fun,

2 Ki aye se atilehin fun awon okunrin ati obinrin ti o ni ife inu peace ni ile Amerika lati kadi gbogbo iwa ibaje yi nipa ireti ninu ogbon ati itosona Olornn alagbara ti yio tikarare yi okan pada.

3 Pe ki a fi ipinnu wonyi ranse si Olotu Ijoba ile Naijiriya ati awon omo egbe igbimo isokan ile Afirika.

Ninu oro re ti o so fun onirohin wa nipa isoji yi, Alaga igbimo isoji Eni Owo Aboyade Cole wi fun onirohin wa pe awon igbimo dupe lowo Olorun fun abaorisi eto won. O ni ipade na yio ji awon elesin Kristi dide ninu orun ese, yio si fun won lagbara lati tan mole won fun awon elomiiran.

WO OJU IWE KEJO

## OTITO INU

### LATI OJU WE KEFA

Emi na ko koko gbagbo nigbati mo gbo liwosan woli na. Mo nilati lo sibe lo fi oju ara mi Opolopo igba ni ntun lo sibe lehin na; bakana ise iyanu nti owo Woli Kogberegbe se pelu adura lasan ni oju gbogbo enia bi ti atehinwa.

A nilati sa agbara ki Woli yi le be awon ile Olorun miran wo nibi ipade won l a t i mojuto awon alaisan. Aimoye eda ni yio ri ohun ti adura n s e fun enia. Ibukun nla gba a ni eyi fun ile Afrika ni asiko yi.

Mo fi tokantokan kesi awon Gospel Team Church nibiti Woli Kogberegbe ti nsise lati gba a laye ki obe fjo miran ti o nfe iranlowo re wo. Aiye aidanijoluyi nwa opolopo Kogberegbe.

## IGBONRAN SAN JU EBO LO

### LATI OJU EWE KEFA

wa dahun wipe nse ni on lo si ile oba lati lo wo omobinrin keta o si wa so fun Baba onisegun ohun ti o sele Baba onisegun si tun wa bi iya na ni gbolohun kan bayi wipe se o ye Iya na si dahun wipe o ye on. Baba si wa so fun iya na pe omo re ni eyiti o wa ni odo oba ti oba ti fi se aya.

Nitorina awon mejeji akoko omo iyi ati omo isu ni won je. Lehin eyi iya na na wa ni on yio ta baba onisegun na lore patkai Baba onisegun na ko gba fun iya yi ohun ti on fe nibe ni wipe o gbo oro si on Baba onisegun na lenu

Eko ti o wa ninu itan yi nipe o ye ki a ma gba imoran awon agba ki a si ma gboro si won lenu. Igboran san ju ebo lo.

Se o nwa ere Rebete?
Kini se ti oko polowo oja re ninu iwe Irohin yi?
Kowe si oga Apolowo oja

# Egbe Ibukun Se ajoyo odun keji



OPOLQPO aw-n enia lo pe ejo sinu ile Olorun ti Christ the King (Anglican) Church ni Apapa Ajegun le ni ojo ose ti o koja yi fun ajoyo nla ti isin idupe-keji ti awon Egbe Ibukun.

Lati igbati a ti da egbe na sile ni awon omo egbe ti nsin Olorun tokantokan nwon ti nwon si nfi tokantokan 'o owo ati ara wo[illegible] Ile Olorun won. [illegible]

[illegible] kan ati obirin talaka kan ti nwon npe ni Beth ninu ijo re. O ni ni akoko ti alufa yi ba ti nwasu ni obinrin yi ma nkigbe soke pe "Eyin Oluwa Logo, Amin.' laika ibawi ati mu u' dake si.

Alufa Babalola ran awon ijo na leti pe bi o tile je wipe a ko gbodo pariwo ninu ile Olorun a nilati mo pe ope je ore-ofe ti a ko le pamo.

O se afikun pe, "jeki awon eni irapada Oloru ni wi be, Awon ibuk un wa wa lati odo Re, on na ni a si nfi ope wa fun nisisiyi.

Ni ipari, o so fun awon egbe Ibukun lati tesiwaju nipa fif ope won fun Oluwa fun anu re lori won.

Ni ibere isin, Alufa na koko ya [illegible] a s o egbe akorin si mimo. Ara [illegible] enia oloye ninu egb[illegible] nwon pese nibi akans[illegible] ni Ogbeni S A. Okusany[illegible] (Baba egbe Ara[illegible]rin Odun[illegible] (Iya egbe)? ati ogbeni N. A Olusoto, (Akowe Agba).

## KOGBEREGBE NDABIRA

GONGO Tun so bi ti atehinwa ni ile Olorun Gospel Team ni Numba 30 Iyala Street Mushin. Nigbati woli Kogberegbe bere adura relose to koja. Ajebidan ni oro ti nti enu woli na jade, A si se gbogbo awon ti o pejo.

Nigbati isin na bere woli Kogberegbe pase pe ki awon alailera to si iwaju awon enia, aisan elomiran nira tobe ti o fi je pe pelu ipa ni o fi duro niwaju woli na lehin eyi woli Kogberegbe gbadura kikankikan, o si ba awon aisan na wi loruko Oluwa.

Lara awon ogbon enia ti o ri iwosan ni ogbeni A.R. Nwosu ti nomba 3 Adeyemi Street Mushin eniti orun ndun fun ose kan ti ko si lesun, Arabinrin Munira ti ngbe nomba 1 Soremekuu St, Mushin ti ese ti nro fun osu meta ati Alake Akotijo lati Abeokuta eniti o ri ni ibule aisan lati odun meta.

Bi isin na si ti pari, gbogbo awon alaisan ti o ti nfun oju po tele fi ayo lo si ile won ti won si nyin Oluwa Olorun ti o fun woli Kogberegbe ni agbara.


## Louson's Electronic Service Engineering

For all repairs of electrical applaiecs:- Television, Radios' Amplifiers' Recorders' Refrgrators and Cookers.

Conversion of any Television Sets to 625 lines and Vise Visa.

Gall at

16 Ikorodu Rd Igbobi
Every job is guaranteed by
D. G. Uduka.
Manager


## SOSI ENU OWA SE IKORE AWON AGBA

Pelu itara, igbona okan ati ilawo ni awon enia fi nkorin pelu ohun ibile ti o dun bi oyin nibi ajoyo Ikore awon agba ti ijo King's Church ni Eko laipe yi.

Ile Olorun na ti nwon fi orisirisi awon nkan se loso kun denu ki isin tile to bere ni dede ago meta osan (3 p.m.)

Orisirisi awon ebun ti awon enia mu wa ni a kojo soju kan nibiti awon enia ti nwo gbogbo re kedere.

Ninu iwasu, Alufa S. A. Akinbo ti ijo Wesleyan Church, Obun Eko, Lagos, ran awon enia leti pe ikore je ipasiparo ibukun Olorun. O tesiwaju bayi pe "Olorun je eniti o nfe lati ma fi funni o si lawo si wa. O mo aini wa, o si nfi fun wa lojojumo."

O ro gbogbo awon enia olope lati wa siwaju pepe pelu ebun ti o joju fun Olorun alagbara.

Bi awon egbe akorin ti nkorin ti won si nto lowowo jade pelu orin "A f'ope f'Olorun"

Olutoju ile Olorun so fun onirohin wa pe idupe na ni iyin at'ogo nitoripe idupe ti odun yi ju ti odun ti o koja lo.

## Canon Asekun Losi Cotonu.

Alufa omo odun mejileladorin ni ti ise alakoso ijo St. Davidi Lafiaji Canon D. K. Asekun fi Eko sile ni ose yi lo si Cotonu.

Alufa na ati iyawo re yio lo ose kan ni Cotonu ni iranti ogoji odun ti won ti gbeyawo

Alufa Canon Asekun so fun onirohin wa pe; Mo ni idunnu ati ope si Olorun nigbati mo ba bojuwo ehin wo awon odun wonyi. Laiseaniani, odun ibukun ni won je. Alufa na ati iyawo re yio pada si Eko ni osu ti mbo.

Ate iwe yi lati owo egbe Crusaders Press Limited, 9, Western Avenue Surulere Olotu Charles Babalola 69, Great Bridge Street, Lagos.